UK Health Security Agency

NHS

# Itọnisọna rẹ si abẹrẹ ajẹsara RSV fun àwọn agbalagba

**Bi o ṣe le daabobo ara rẹ nipa gbigba abẹrẹ ajẹsara Aarun Ailefojuri Ọna Ọfun (RSV)**



**Alaye lori abẹrẹ ajẹsara RSV ọfẹ fun awọn eniyan ti:**

- o pe ọdun 75 l'ọjọ ori ni ọjọ 1 Osu Kẹsan 2024
- o ti pe ọdun 75 si 79 l'ọjọ 1 Osu Kẹsan 2024

## Kini RSV?

Aarun Ailefojuri Ọna Ọfun (RSV) jẹ aarun iranmọ ti ọna ọfun ati ẹdọ foro. Iranmọ RSV saba nfa awọn ami aarun to sunmọ otutu, eyiti o pẹlu ikọ, ọgbẹ ọna ọfun, sínsín ati imu riro ati dídí. O tun le jẹ ki o maa min lokeloke tabi má min kanlẹ ti yóò sì yọri si otutu aya ati awọn ipo miiran ti ngba ẹmi. Kosi pato itọju kankan, ati wipe ọpọ awọn aranmọ yóò sàn funra wọn. Ẹgbẹẹgbẹrun awọn agbalagba nilo itọju ile-iwosan fun RSV lọdọọdun, ti diẹ ninu wọn yóò síì kú. RSV le gboro síi nínu àwọn ènìyàn tóní àwọn ipò ìṣègùn bíí ààrùn ọkàn tàbí ẹ̀dọ̀ fóró tàbí ìrẹ̀wẹ̀sì ètò ìdásílẹ̀ àìlera.

Aranmọ RSV wọpọ ninu awọn ọmọde sugbọn o buru julọ fun awọn ọmọ ọwọ ati fun awọn agbalagba.



## Bawo ni o ṣe le ni RSV?

Awọn aranmọ RSV le waye jakejado ọdun sugbọn àwọn iṣẹlẹ náà ga julọ ni gbogbo akoko otutu.

RSV le tan kiri nipa ikọ ati sínsín. O le ṣe iranlọwọ lati dena itanka awọn kokoro arun ailefojuri nipa fifi ọwọ bo ẹnu ati imu rẹ nigbati o ba wukọ tabi sín (pẹlu ìwé fẹ́lẹ́fẹ́lẹ́ kan, tabi sinu kọrọ igunpa rẹ), o si le fọ ọwọ rẹ loorekoore tabi din ewu kiko kokoro aarun ailefojuri. Koda pẹlu awọn odiwọn wọnyi o le soro lati yago fun iranmọ RSV.

Ọna to dara julọ lati daabobo ara rẹ ni lati gba abẹrẹ ajẹsara naa.

## Bawo ni abẹrẹ ajẹsara naa ṣe nsiṣẹ?

O fẹrẹ jẹ wipe gbogbo awọn agbalagba ni yoo ni ọpọ awọn aranmọ Rsv ni akoko aye wọn. Abẹrẹ ajẹsara kan yoo ran ọ lọwọ lati ṣe afikun aabo gẹgẹbi o ti de ẹgbẹ ọjọ-ori ti o l'ewu aranmọ RSV lile julọ.

## Njẹ awọn eniyan miiran ti o yẹ fun abẹrẹ ajẹsara wà?

A fun awọn obinrin to loyun ni abẹrẹ ajẹsara lati daabobo awọn ọmọ wọn lọwọ RSV. O le ka itọsọna si abẹrẹ ajẹsara RSV fun awọn obinrin oloyun nibi:

**www.gov.uk/government/publications/respiratory-syncytial-virus-rsv-maternal-vaccination**

## Nję mo nilo lati gba abęrę ajęsara lọdọọdun?

Bęękọ, abęrę ajęsara kan yę ki o fun ọ ni aabo didara fun ọdun dię.



## Tani ko gba abęrę ajęsara RSV?

Gbogbo ęniti o npe ọdun 75 l'ọjọ tabi lęyin ọjọ 1 Osu Kęsan 2024 ni yoo gba abęrę ajęsara RSV kan. Eyi waye nitori awọn agbalagba wa ni ewu idiju lile lati RSV. O si le gba abęrę ajęsara titi di ọjọ saaju ki o to pe 80.

Fun ọdun eto akọkọ, a o tun fun awọn to ti pe ọdun 75 si 79 l'ọjọ ori ni abęrę ajęsara l'ọjọ 1 Osu Kęsan 2024 gęgębi ara eto imubọsipo.

## Bawo ni awọn eniyan ti ko tii pe ọdun 75?

Awọn ọdọ yoo gba abęrę ajęsara nigbati wọn ba de ọjọ-ori 75.

## Nję mo le gba abęrę ajęsara RSV ni akoko kanna ti mo gba abęrę ajęsara COVID-19 tabi ọfinkin?

A ki nsaba s'eto fifunni ni RSV ni akoko ipade kanna ti o gba abęrę ajęsara COVID-19 tabi ọfinkin.

Ni awọn ipo işegun kọọkan, dokita tabi nọọsi rę le pese wọn fun ọ ni akoko kanna.

## Nję mo le gba abęrę ajęsara RSV ni akoko kanna ti mo gba abęrę ajęsara shingles tabi pneumococcal?

Bęęni, o le gba awọn abęrę ajęsara wọnyi ni igba kanna.

## Nję ęnikęni wa ti ko yę ko gba abęrę ajęsara?

O fę ję pe gbogbo eniyan lo le gba abęrę ajęsara, sugbọn sọ fun dokita tabi nọọsi naa bi o ba ni aibaramu lile, tabi eyikeyi eronja naa.

Bi o ba s'aisan kekere bii otutu o le gba abęrę ajęsara naa, sugbọn bi ara rę ko ba ya tabi ni iba, dokita tabi nọọsi le gba ọ niyanju lati duro titi ara rę yoo fi ya.

## Nję abęrę ajęsara naa le daabobo mi patapata?

O ti han wipe abęrę ajęsara ti din aaye ijiya rę ku kuro lọwọ aarun RSV. Pęlu gbogbo awọn oogun, kosi abęrę ajęsara to peye patapata awọn eniyan kan si le tun gba RSV biotilęjẹpe wọn ni eto gbigba abęrę ajęsara kan. Bi o ba gba RSV, ko yę ko le ju.

## Bawo ni ma şe ni aabo pę si?

Ninu awọn iwadii işegun naa, abęrę ajęsara RSV pese aabo didara fun o keere tan ọdun 2, o si yę ki o pę gidigidi.

## Nję maa ni awọn idiju kankan?

O le ni ọgbę ọna ọfun, ara pipọn tabi wiwu ni oju abęrę naa fun ọjọ kan tabi meji leyin gbigba abęrę ajęsara naa.

Ni akoko ilo akọkọ ni orilę-ede US, a ti fun awọn eniyan ni abęrę to ju miliọnu 12 lọ. Wọn ti jabọ ipo eto ara ti ko wọpọ ti a mọ si awọn aami isajeji Guillain-Barré to yọri si ailera, bii awọn isęlę 10 fun gbogbo abęrę ęgbęlęgbę ti a fun awọn eniyan. Ipo kanna le tun sęlę lęyin iye awọn aranmọ to wọpọ ati awọn abęrę ajęsara dię sugbọn lapapọ o laabo fun ọ lati gba abęrę ajęsara ju ki o ko aranmọ RSV lile lọ.

## Kini ki n şe nisinsinyi?

Onişegun rę yoo kan si ọ lati s'eto ipade kan fun abęrę ajęsara RSV rę nigbati o ba pe ọdun 75.

Bi o ba wa ni ọjọ-ori 75 si 79 ti o ko si tii gba iwe-ipe, kan si Onişegun rę lati ş'eto ipade kan lati gba abęrę ajęsara RSV rę.

## Níbo ni mo ti le gba ìwífún síwájú síi?

O le ka iwe iwifun pelebe fun abęrę ajęsara RSV ti a npe ni Abrysvo nibi:

**www.medicines.org.uk/emc/product/15309/pil**

Bi o ba ni awọn ibeere siwaju sii, ba nọọsi, GP tabi ikọ ilera rę sọrọ.

O le jábọ̀ àwọn ìdíjú tí o furasi lórí ojú-ewé káádì Yellow (Yellow Card) tàbí nípa pípe 0800 731 6789 (agogo 9 òwúrọ̀ si 5 ìrọ̀lẹ́ Ọjọ́ Ajé sí Ẹtì) tàbí nípa gbígba ápùù Yellow Card sílẹ̀ sórí Apuu

**www.mhra.gov.uk/yellowcard**

© Crown copyright 2025. Version 4. UK Health Security Agency Gateway Number 2024982. Product code: V2C24RSV01YO Yoruba. 2P 130K FEB 2025 (APS). To order more copies of this asset, please visit: www.healthpublications.gov.uk or call 0300 123 1002. This leaflet is available as a BSL video, and audio file, in braille, large print and translated into 30 community languages.